## Owe

Owe ni ẹṣin ọrọ, lọjọ ti ọrọ ba sọnu owe ni a fi nwa. Nigbati eṣinṣin njo Kudayisi, ẹnikan ko gbọ ẹnikan ko mọ, ṣugbọn nigbati Kudayisi wa jọ ẹṣinṣin ni gbogbo aiye wa gbọ, ti aiye mọ

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

Oja ko ta ema polowo oja yin sinu Iwe Irohin Imole

VOL. V No. 300 MONDAY SEPTEMBER 11 — SEPTEMBER 17 1961 KỌBỌ MEJI (2d)

# Okunrin kan lu iyawo re ni ilu bakaya tan o pa a, o si binu lo pokunso

IDOMA:- A GBỌ IROHIN WIPE, OMỌKUNRIN KAN BA IYAWO RE JA, IJA NA SI PỌ JỌJO, AYAFI NIGBATI ỌLOPA DA SI, TI O SI MU ỌKUNRIN NA LỌ SI ITIMỌLE, ṢUGBỌN WỌN GBA IDURO FUN, O SI PADA WA SILE.

OBINRIN NA TI O NJẸ OGELE LỌ LỌ ROHIN FUN AWỌN ỌLỌPA WIPE, ỌKỌ ON LU ON NI ILU BAKAYA NIGBANA NI ỌLỌPA TO WA LỌ MU STEPHEN TI IṢE ỌKỌ OBINRIN TI O LU NI ILU BAKAYA NA.

Nigbati ọkọ obinrin na pada dele, lo ba yọ ọbẹ, o ni ki Iyawo na fo ki o nṣo, nibiti iyawo na gbe nsalọ ti o de eti odo kekere kan, ibẹ ni ọkọ rẹ na gbe ba a, o si gun ni ọbẹ, ki o to wa lọ pokunso nitosi ibẹ na.

**Ijoba ngbero lowolowo yi,** lati da awọn elere bọlu ti Ilu Oyinbo duro, nitori ki a le da awọn elere bọlu ti ilẹ wa sile, ṣugbọn ọrọ na ko iti le jẹ ṣiṣe.

✤ AGBỌ IROHIN WIPE, OMỌ ODỌ TABI IRANSẸ kan ku sori ibusu rẹ, ni opopo ọna Yaba, iyawo rẹ ni a gbọ pe o mọ bi ọrọ na ti se rin. Iṣẹ ransẹ ni a gbọ wipe oku na nṣe ni Apapa, o lọ sibi iṣẹ, o si pada bọ wa sile laisi ewu, ko ṣe okunrun, beni ko ṣe amodi ki Ọlọjọ to de si.

Bakanna ni a gbọ irohin wipe nilu Agbani, leti ilu Enugu bẹni ọkunrin kan npada bọ lati oko ọdẹ. Bi o ti mbọ lori awọn enia ti nwọn pejọ nibikan ti awọn nworan awọn ti o njọ fun omọ oloku kan o si duro lati woran. Ọkunrin ọdẹ na gbagbe pe ibọn on nbẹ lori akọ o gbagbe ara rẹ si duro, awọn ti njo na ṣe ohun ti o pa ni lẹrin bẹni ọdẹ yi si fi gbogbo ara rẹrin tobẹ ti ibọn fi bọ sile, o si gbina. Agbọ pe Ọdẹ na salọ, awọn Ọlọpa ko ri ẹnikankan mu. Eniti ibọn ba wa nile Alaisan.

## Bawo ni Olopa tise rin ki nwon to ti ilekun mo sinu ile

ABẸOKUTA:- Omọkunrin kan ti o gba iṣẹ Ọlọpa pataki ni a gbọ wipe awọn enia ti ilẹkun mọ sinu yara ati wipe o tọwọbọ iwe pe on gba poun meji owo ẹhin.

Awọn Ọlọpa fi ẹsun mẹta sun Ọlọpa pataki na bayi pe o ṣe aṣemaṣe o fẹ wọ inu ile enia lati wo bi ohun ti o lufin ba wa nibẹ laigba iwe aṣẹ dani ati wipe o ji poun meji lọwọ obinrin kan ti o njẹ Janet Eletu. Bi a ti gbọ ti ọrọ na lọ niyi, Ọlọpa pataki na mu obinrin ti a npe ni Eletu yi, nitoripe awọn ri oti bọlugi lọwọ rẹ. Gbogbo enia si bẹbẹ fun omọ obinrin na, ṣugbọn a gbọ pe Ọlọpa patak na so pe ayafi bi wọn ba le mu poun marun wa Owo yi ni wọn ni ki on wa gba ti wọn fi tilẹkun mọ on.

## Victor Olaiya ati awon Osere re fe lati lo be ile Kongo wo



Fabulous Victor Olaiya

EKO:- A gbọ Irohin wipe Ọgbẹni Victor Ọlaiya alulu bi alara ati awọn Oṣere rẹ ẹniti a ti fi igba gbogbo gbọ ohun fere rẹ ti o fi nkọ orin aladun ti okiki rẹ si ti kan nipa iru awọn orin ti o ma nkọ li o nlọ ṣe abẹwo awọn Ọmọ Ogun ilẹ yi ti o ti lọ ṣe atipo si ohun lati ọjọnjọ yi wa. Eyi ni akọkọ igbati Olaiya ati awọn akọrin rẹ yio lọ si ilẹ ọna oke-okun bi o ba de ọhun, yio fi orin rẹ ṣe idalaraya fun awọn jagun-jagun wa ti o mbẹ ni ọhun ati lati korin fun awọn ọlọpa ti nwọn lọ ṣe ilaja lọhun.

Enikan bere wipe nigbati nwọn ba de ilu Kongo elelo ni nwọn o ma fi wọle wa wọnu Ṣugbọn ọgbẹni Ọlaiya sọpe, on ko iti leṣo ohun kan nipa rẹ, iba wipe ki awa pẹlu ara ilẹ na sani irẹpọ si ara wa. Aye ọjọ mẹsan pere ni ijọba fun Ọlaiya pe ki nwọn lo lọhun ki nwọn to ma pada bọ wa si le. Nwọn o ṣere ni Kongo, ni Matadi ati ni Leopolsville.

Ọlaiya ati awọn Oṣere rẹ yio fi Ilu Eko silẹ lai pẹ ọjọ lẹhin ti aba ṣe ere ọdun kan ti Naijiria gba Ominira tan ni yio wa lọ si Kongo.

# IROHIN IMOLE

ẸSIN ORO WA:- "IMOLE DE. OKUNKUN PARADA"
Editorial Works & Office
16, Bngbose Strt, Lagos
Telephone: 21985
United Kingdom Representative
Publishing Distributing
177, Regent Street, London W. 1.
IVAN F. LUCKIN 6, LAUREN Pountney
Cannon Street, London, E. C. 4
U. S. A. Representative.
REGIS BOBONIS, 2528 MAMON ST.
PITTSBURGH PA. U. S. A.


## Ominira ni awa Naijiria gba ni tabi Omi-Inira

AKI GBOBO ENYIN OLOTU METETA TI MBẸ NILU NAIJIRIA PE Ẹ KU IṢẸ ILU WA NAIJIRIA ILU AWA ENIA ALAWỌ DUDU. A SI TUN KI DỌKITA NNAMIDI AZIKIWE KU ABỌ IRIN AJO RẸ TI O ṢẸṢẸ DE, BAKANNA NI A SI tun ki Ọlọla wa Megirima Alhadji Tafawa Balewa pe o ku iṣẹ apapọ ṣe rẹ, o ku Ọgbọn ati Lakaye.

Ohun pataki ti a fẹ bere lọwọ gbogbo ẹnyin Olotu wa ni wipe kini Itumọ ooi ẹjọ ọla aroye lati ọjọ kini oṣu kẹwa ọdun tokọja (1st october 1960.) ti a ko gba oju mọ iṣẹ tibitibi ti o jẹ tiwa ti awọn ajoji nba wa ṣe bọ fun ọdun gbọrọ sẹhin ti a si gba lọwọ wọn ti a kọ si mu oju ṭo bawo ni ko ṣe ni baje lọwọ awa onikan.

Lati ọjọ ti a ti gba Ominira wa kosi ile ẹjọ kan ti nwọn ko nda ẹjọ ododo awọn adajọ ko ngbe si ọtun bẹni ki nwọn ko ngbe si osi, lati igba Ominira wa na ọgọrọ enia lo ti di alaini. ọgọrọ lo si ti fi ẹmi rẹ ṣofo danu laiko mọ ohun ti wọnle da lẹhinọla, sibẹsibẹ ọgọrọ lo si mbẹ ni Itimọle lati ọdun tokọja Ha! kilo ṣe a ba le sọ ara wa di Ọlọrun bi? Sugbọn awa fẹ ki olukuluku wa L ọ m ọ d o ati agbagba mọ daju pe idajọ ati ẹsan mbọ wa ba olukuluku wa laiye yi na ni.

Lakotan ọrọ wa ọsẹ yi a bẹ gbogbo ẹnyin Olotu mẹtẹta ki ẹ fimọ ṣe ọkan ki ẹ fi ọwọ wẹ ọwọ pọ ki ọwọ yin le mọ. Ki awọn ti ọpọlọ wọn pe faramọ awọn ti tirẹ ko pe ki awọn ara okere le ma gbọ irohin yin ni rere.

A kan ngbọ pe g b o g b o yin lo nfo lọ pe awọn ara okere wa lati da iṣẹ silẹ nilu wa fun anfani ara nikan kọ o wa fun awa ara Ilu Naijiria pẹlu.

# SE BOTIMO

## APA KEJI (2)

Lati Ọwọ: FUMILAYỌ KOFOWOROLA

Nigbati awọn mejeji ro siwaju ti nwọn ro sẹhin ni nwọn ba tọ babalawo kan lọ ni arin ilu wọn, nigbati awọn de ọdọ Babalawo, o ki wọn dada o si gbe eni fun wọn. Nwọn joko, nigbati o to iṣẹju meji si mẹta ti wọn ti joko, ni Babalawo wa bere lọwọ won, o ni ẹnyin ara ṣe ọ wa ri mi ni? Ṣebotimo si da lohun wipe bẹni alagba Babalawo tun bere pe fun kini o? Ṣebotimọ tun dalohun pe awọn wa wo iṣẹ ni o, ni babalawo ba ni ki awọn mejeji daniyan papọ, lẹhin ti nwọn sọrọ si inu wọn kẹlẹkẹlẹ wọnju silekookan sinu ọpọn Ifa.

### BABALAWO TE IYANRIN

Bi Baba ti tẹ Iyanrin tan, odu ti o jade l'oju ọpọn sọ bayi pe, Tete lowo ki o ma ba lowo mọ lailai, Ifẹsọ l'owo kowo ba le ba ọ kalẹ, ni o difa fun awọn akọ apon meji nigbati wọn tọ Orunmila Bara agbọnmiregun wa lọjọ kini ti nwọn bẹresi sọkun alaini owo lọwọ.

Orumila, a tun ori ẹniti ko sunwọn ṣe sọ fun wọn bayi pe ki nwọn lọ ni suru, ogun Olọna ọla yio pese owo tutu fun wọn, sugbọn suru l'ẹbọ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸFA

## Awon enia meji lo bura niwaju orisa Sango

Lati Ọwọ: LATIFU MUSARI
NONBA 97, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

ẸGAN: A gbọ wipe awọn enia meji ti nwọn jẹ oni bara ara wọn, jijọ lọ bura niwaju Ṣubulade oriṣa Sango ti a npe bẹ ni Ilu Egan. Obinrin kan ota ẹja panla ni arin ọja Ẹgan, bẹ ni Ajọke onibara rẹ de, o ra ẹja panla mejila lọwọ ọrẹ rẹ oni panla.

Bi obinrin oni panla na ti nwo ihomiran, bẹni Ajọkẹ ji ẹja nlanla meji, o we mọ aṣọ laiko mọ pe ọmọbinrin eleja na ti ri on. Nigbati ọmọbinrin na yiju pada, o fi ohun jẹjẹ sọ fun Ajọkẹ pe, haba! Iwọ ọrẹ mi, o si ji mi ni ẹja meji tan, Ajọkẹ taku pe ọrọ ko ri bẹ. Bi ere bi ere, ọrọ na di ohun ti ero pe le wọn lori, para ti Ajọke ma dahun, o wiṭe, Emi ko nṣe ole, bẹni nko si jale ri, bi ko ba da nyin loju, jẹki a jijọ lọ bura loju Ṣubulade.

Laiṣa ọrọ gun, ẹnikini bura, ẹnikeji bura pe ki Sango pa on bi on ba jale, lẹhin ti wọn bura tan, Iya Ṣango da ọjọ meje fun wọn pe, Idajọ na di ẹnin ọjọ meje.

Ọrọ ko dun nilu Igando nigbati ọjọ keje pe, ti ojo bẹrẹ si rọ, ara ti o pa Ajọkẹ yi, ẹ mẹta lo san lẹralẹra Awọn Babalawo yẹ Ifa wo, won ni ole loja, awọn oni Ṣango ni o jale mi. Amọkunkun ṣole ti o ro pe oju ọba aiye ko ri on, bi ọba aiye ko ri ọ nkọ, ti ọrun ko ha nwo ọ ndan?


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN PE NI:-

RICHALFT FUN ARUN EJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yatọ patapata si awọn RọbiRọbi Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo K o k o r o buruku ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" bi Mọnọmọno.

Meji rẹ kosi ninu gbogbo awọn Egbogi ti wọn npe ni TỌNIKI Ejẹ ti wọn si nta kakiri ni owo pọọku adinọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo. Iyẹn ṣe ewọ awa ki ta awọn egbogi bawọn yẹn rara tabi ti wọn npota ni ilẹ yi.




Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi bawọnyẹn a ma ojulowo egbogi stata ti a nranse fun tita lati awọn ilu J a m a n i Faranse ati ti awọn Tatabulu Itali jọ. Mọdaju wipe bi Ejẹ Ara ko ba mọ daradara awọn amọdi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ Laku r e g b e orisisi Inarun, Ojuṣiṣu tabi didun Jẹdijẹdi Akọ Iba arun ẹdọki Ayadidun Itanpara, ekuru lara.

Ara riro, LapaLapa Egbo ẹ s ẹ, Amodi Apo ileitọ ẹhin didun tabi Ibadi riro pẹlu egbogi Rishaleti a ma pa gbogbo Kokoro buruku ti o wa ninu Ejẹ ara patapata yio si fọ ẹjẹ ara rẹ mọ tonitoni pẹlu Ṣa dan Igo rẹ kan wo lara rẹ dajudaju iwọ yio ma rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu nigbakugba.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADESỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN

# Ajegboro Dagba Nki Nyin o!

MO KI gbogbo ẹnyin okawe mi, emi Ọkunrin Jainjain, Iroko Jainjain, mo tun de loni, emi Ajẹgborodagba tun ma de, Ọkunrin ti a fi ṣe pe sọ okunrin, A nju wọn ko se wi lẹjọ, imọ lara ko tan bọrọ, mo gbe tana dunu mo nawọ mu omiran, Ẹnyin onkawe mi, tabi Ẹ g b ọ.

HẸN! ẸNYIN OBI? Ẹ RI OJU OLE, Ẹ OMU

Ohun ti o fa akale mi ti ọsẹ yi ni wipe o ti to ọjọ mẹta ti mo ti ma ri iru iwa ti mo fẹ sọ yi lọwọ awọn Obi ode oni, Iwa na ni pe, ẹnyin obi ẹ ri oju ole ẹ ko mu ọmọ yinko se agba fo o ko asọ wa sile, o pọ pupọ ninu awọn obi ode ti oje pe awọn ni wọn ba ọmọ wọn lori jẹ nipa pe ọwọ wọn ni ọmọ wọn ti loyun nigbati oyẹ pe wọn ri ti o nlọ si ode oru tio nko asọ olowo iyebiye wọle wọn ko fura si nigbati ko jẹ pe awọn ni wọn ra nkan wọnyi fun wọn ko si bere ibiti oti ri owo fi ra wọn.

Obinrin miran ni oba ọmọ rẹ lori jẹ nipa ti o ba ri owo lọwo rẹ ati asọ O l o w o Iyebiye ko ni bere ibiti oti ri eyiti ko ba fi bere, aoi jọwọ, Raliatu? O si fun mi Tọrọ ni bẹ yẹn ki fi ra Burẹdi, bi osi jẹ asọ ni yio ma ni ọmọ mi ma ra asọ to dara, o ma gbajumọ bi o se ma pọn ni yẹn? Alakọri ko le ma ri owo Burẹdi g b a gbogbo gbati o gba nkan wọnyi ti osi ri bi oti ra Asọ ko sọro ti o fi jẹ pe yio bẹ ọmọ na pe ki o ra Buba kan fun on na. Ṣugbọn nigbati ti bi bawa de afa igbe ta ori nigbati Ọkunrin ba wa ọmọ rẹ walẹ ko ni s ọ r ọ o Ọkọ nfun lowo o, ko wi nkankan Baba ko mọ nkankan o lọ si ode oru, ko joko kawe nile ko ni ba wi ko si sọ fun, ṣugbon ti o ba wa di pe oloyun yio ma kigbe kiri, Awa lanu silẹ bi Aja mi lo pa ama rojọ kiri.

Nigbati omo rẹ nlo Bonfo, Rapa, Basọ site ati orisi risi asọ MereMere ko sọrọ odi oyun o rọjọ kiri bẹ sini kise pe ọmọ rẹ ti sisọ. Obi miran yio ma lẹhin nigbati Ọmọ rẹ ba nlo asọ Yebiye, eyiti Baba ko ti ri iru rẹ lo, Baba nsare kiri bi yio ti so san owo ile ẸKỌ, Bonfo sile, ni ọmọ nlọ gbowo lọwọ Ọkunrin kakiri ti Iya si mọ nipa gbogbo rẹ, ṣugbon oyun ni o t u n a aṣiri awọn Obi Oloriburuku ti oba Ọmọdebirin lori jẹ, Ẹ lo miran ti lẹ ma nsọ pe asọ lọrẹ awọ. Bi baba ba nba Ọmọ na wi nisẹ ni Iya rẹ ma tapatapa ti yio si ni ki o fi silẹ, pe ko si eyiti o kan nibẹ obinrin ni, Iru awọn Obi ba wọnyi nhu rufẹ iwa ba yi ṣe bẹ loju emi 'Ajẹdagba' to jẹ pe baba ko gbọdọ ba Ọmo rẹ obinrin wi nisẹ ni yio fẹ ba baba na ja ti yio si ma ka labu.

Nitorina mo fi iwe yi bẹ gbogbo ẹyin obi ti o ba nhu rufẹ iwa bayi ki olọ jọwọ kuro ninu rẹ ti o ba nfẹ ki Ẹlẹda ọmọ na ma sepe fun lẹhin ọla, nitori gbogbo ni ọmọ, to ba dara fun ọmọ kan fun Baba ati Iya ni.

# Awon Aganyin nko bi a se nkan Oko nilu Oyinbo



Enia Mẹtala ninu ọmọ ile awọn Aganyin lo lọko isẹ bi ati se nkan ọko Oyinbo ni abẹ awon oyinbo ti onkan oko ti nwon npe ni T. Machison LTD. ni eti EBUTE-RIVER TYNE ni adugbo ti nwon npe ni Gateshead.

A gbọ pe awọn Ọmo ilẹ Aganyin mejl ti a nwo nwon yi ni oye lori pupo. Ọkan nsẹ Welder ekeji nse Draftman, oruko won ni E. A. Addo ati C. A. Tẹtẹ.

# Petepete T'ana ni popa

## Ẹ FI OJU TO AWỌN ỌMỌBINRIN YIN DADA

Iwa buruku kan wa larin ẹnyin Obi (Parents) ti ẹ wa lati Ilu Oke; Iwa buruku na ni wipe ẹnyin Obi ki jẹki awọn ọmọbinrin yin lọ si Ile Ẹkọ. Dipo ki ẹ ran wọn lọ si Ile Ẹkọ, ẹnyin yio ma sọ pe, ki wọn ma lọ kọ isẹ Telọ (Tailor) Ha! ẹru ko tilẹ ba ọ Iwọ Obi ti o ni ki ọmọbinrin rẹ ma lọ kọ isẹ T e l ọ; Mo bere lọwọ rẹ asọ melo ni ọmọ rẹ fẹ ran ki o to di enia pataki? Ero to wa lọkan ẹ n y i n Obi wọnyi ni pe ọmọbinrin ki mọwe dada, ṣugbọn ero ti ko mu ọgbọn dani patapata gba ni eleyi jẹ, Sebi Iwọ ri ọmọbinrin ti o nwa moto ayọkẹlẹ kakiri niwaju Ile rẹ, mo bi ọ, njẹ isẹ Telọ lo kọ ti o fi de aye to wa yẹn? O w e kan wa to sọ pe: Ohun ti Ọkunrin le ṣe, obinrin papa le ṣe, mo mọ pe kiṣe pe o ko ni owo lọwọ, ṣugbọn Iwọ ro pe ọmọ rẹ obinrin ko yẹ ki o kawe a fi isẹ Telọ lo yẹ.

Ṣugbọn mo tun bere lọwọ rẹ pe asọ melo ni ọmọ rẹ fẹ ran ko to le di enia pataki laiye? Mo ke si Iwọ Obi ti ọmọ rẹ nkọ isẹ T e l ọ pe irọ ni patapata gba a ni o npa, Isẹ Telọ ko le gbe ọmọ rẹ de ibikankan! Otitọ ni mo sọ fun ọ, Ẹ lọ loni Monde (Monday) yi ki ẹ si mu gbogbo awọn ọmọ yin kuro nile Telọ ti o ti nkọsẹ, ki ẹ mu wọn lọ si Ilewe dara-dara. Ẹniti ko ba mọ ohun ti yio ṣe lati ran ọmọ rẹ lọwọ, ki o kọwe si mi.

DELE ATỌLAGBE
c/o Irohin Imolẹ Office,
16, Bangboṣe Street Lagos.

Lọsọsẹ, pẹlu ogo Oluwa ngo ma fun ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ni amọran bi ẹ ba bere.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN :FARANSE
TI A NPE NI -
"UROXAL"



Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile itọ itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pipọn tabi rirun, lakuregbe, Ibaradi wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣora ki awọn eleru tabi awọn oni robi-robi ma ta oriṣi omiran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara o!

Owo rẹ jẹ Ṣile Mẹfa abọ 6/ 6d owo ọkọ sile meji abọ (2/-6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYỌ IBADAN.

# EGBE IMOLE AIYE

Esun ọrọ wa:- "IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA"

## ORO IYANJU

Mo ki gbogbo ẹnyin ọmọ 'kare o-jire, papa ẹnyin ọmọ ẹgbẹ I m ọ l ẹ Aiye, ẹ ku orire, ẹ si ku afojuba eni iwe yin, mo ni ero pe gbogbo yin lo ti mọ aye rẹ ninu ẹgbẹ na.

Mo fi iwe mi yi ki gbogbo ẹnyin ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ papọ, Ọlọrun ko tan Imọlẹ rere sile ẹnikankan wa. Olọrun koni jẹki a ṣẹ, Inu mi dun pupọ nigbati mo ri iwe yin pe ẹ fẹ jẹ ọmọ ẹgbẹ. Odua yio gbe yin.

Lati Ẹnu:—

L. A. B. BABALỌLA.
Oludasilẹ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ọrọ mi si yin ni po lati ọsẹ yi lọ oju ewe yi ti wa fun ọ m ọ ẹgbẹ lati ma sọrọ sinu rẹ pitori Olotu iwe Irohin Imọlẹ ti fi oju ewe na jin ọmọ ẹgbẹ. Ṣugbọn nu awọn ohun ti a nfẹ ni awọn orọ ti yio kọ si lọgbọn tabi Itan, alọ, Irohin Imọlẹ Owe Yoruba Akarẹrin, ati ọrọ ijiti tabi amọran, aye si wa lati bere nkan to ba ru ọ loju lọwọ akọwe agba.

Ti o ba ma kowe, jọwọ kọ ki o han rekete ki osi tipe o kọ daradara maṣe kọ irohin ti oju rẹ ko to, ki o fi ran ṣẹ si akọwe agba pẹlu orukọ rẹ ati aye rẹ ninu ẹgbẹ na (Numbers)

Ki nto pari ọrọ mi mo fẹ sọ fun yin nipa ti Ipade ti a wi ki ṣe nisisiyi ṣugbọn ojọ to ma ya a o jẹ ki ẹ tete gbọ. a ko si ni tẹ oruko gbogbo ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ jade mọ ṣugbọn ti o ba nṣọrọ oruko rẹ yio ma jade ninu rẹ.

Nitorina a o mọ eniti ọrọ rẹ tabi Itan rẹ yio d a r u ju. Ebun yio si wa fun ruleẹ ṣui bẹ.

## Owe Akarerin

Lati Owọ:- ABIỌDUNN TIJANI
No. 2. Ọmọ Ẹgbẹ Imolẹ AIYE

Abẹrẹ sọnu oulo bẹ Sango, Sango ni on agba Eran Agbo ati Akuko Adiẹ ki on to le bawa abẹrẹ Elepinni.

Ọmọ toku nikekere ojulokan, Bo dagba to darugbo, Iku na joma mu lo, Bi ko ku lẹto aku ilile.

Afoju ni won wao dele, oni ṣugbọn ẹa, Injkosi torun to nmu on loni, on obagwoju oluwarẹ dada, Igbati koyi sun nko, talo fi oju ri.

Iya Akura yo nijo ọran kosunwon o ni on dupẹ omo on kokuku niOko debi ti cina daran si on lorun.

OJU EWE YI FUN OMỌ
EGBẸ IMỌLẸ AIYE

Jowo tete ma kọ oro rẹ ki a si ma tete ri gba. Ko Oruko ati Nomba rẹ.

## IGBESI AIYE SILE-KAN

Lati Owọ:- A b d u l l a h i Awẹlọnjẹ
No. 1, Ọmọ Egbẹ Imọlẹ Aiye

Olotu inu mi yio dun ti o ba le gba Itan mi yi laye lati jade ninu Iwe rẹ oloyin mọmọ yi, Ọlọrun ko ni gbe olori buruku sibi ise yin, Ọba Ogo ko ni jẹki e ṣiko, ẹ o si ni si rẹ, Ọkọ Oba ko ni sa gbogbo wa lẹsẹ o. Amin.

Bayi ni Itan na lọ: Emi ni Ṣilekan a ṣe mi jade lati inu ẹrọ ni Ilu Oyinbo ninu ọdun 1960. Nigbati mo de silu Eko, ni Ile Ifowo pamọ si, ni akọkọ ko wa lọ, mo si lo tobi ọsẹ meji nile ki wọn to ma fi wa parọ awọn owo atijọ lọwọ awọn enia, nigbati o si kan emi, Oniṣowo kan ni o wa, ti o si gba wa pẹlu awọn aburo mi ati awon ti o jẹ ẹgbọn fun mi, o si ko wa sinu apo kan, nibo eyiti o r u ko jẹki a gbadun nigbati o dele, o si fi wa han awọn ẹbi rẹ, gbogbo wọn nyọ mọ wa, titi o fi tun gba wa pada lọwọ wọn. Ni ọjọ keji o mu mi fun o m ọ rẹ ki o lọ fi mi ra Burẹdi wa, bayi ni mo di ero ọdọ Iya Burẹdi o, mo lero pe ngo ma ri Burẹdi jẹ ni, ṣugbọn nko ri jẹ rara ni ọjọ keta o si fi mi ra B a t a pẹlu awọn iyoku mi, ni o ni Bata yi ba fi tọrọ fun Afọju kan, ni Afọju ba tun fi mi ra Tuwo ni ọjọ kanna yi o.

O si wa rẹ mi pupọ lọjọ na. ni mo ba bọ silẹ lọwọ Iya o ni Tuwo ti moto si tẹ ori mi, ni oju mi ba dan. Ọkunrin kan si ri mi, ni o ba mu mi lọsi Ile Ifi owo pamọ si, ni wọn ba tun da mi pada si Ilu Ọba o.

Mo si wa labẹ titun ṣe lọwọ o, bi ara mi ba da ngo tun yọ si Eko lọjọ kan o.

## Awon Omo ile Naijiria lo se abewo ibiti a gbe ti nko ise Scouts



Awọn enia dudu ọmọ ilẹ Naijiria mẹrin ti a nwo ninu aworan yi ni awọn lo ṣe abẹwo ibiti a gbe nkọ awọn ọmọ Scouts ni iṣẹ wọn nibiti a npe ni Gilwell Park.

Orukọ won ni wọnyi, Malam Idaro,Binta M. B. E., F. J. Do k u n b ọ, Anthony Manuba, ati omidan Veronika Oppia. Orukọ Oyinbo ti o mba wọn sọrọ ni Ọgbẹni A. Wingrove.


AWON IWE KO SE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN;
IWE ADURA ISEGUN AWON AJE;
IWE IFA AGBON-NIREGUN, IWE ITUMO ALA PELU IWADI NKAN;
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU:
★ ★ ★ IWE ADURA TETE DA MI LOHUN:-
★ ★ ★ IWE ITAN ABALAIYE ATI TI ISEDALE.

KOWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA


E ma ka Iwe Irohin Imole nigba gbogbo

# Ye Irawo re wo

Eyi ni asọtẹlẹ ohun ti yio ṣẹlẹ si awọn ẹniti a ba bi ninu osu nwọn yi tabi ti o mbọ wa ṣ ẹ l ẹ tabi o ti sẹlẹ larin ọsẹ yi:- Ẹniti a ba bi larin oṣu yi

July 23 - Aug. 22 (Leo) Ọrọ ibinu kan yio ṣẹlẹ si ọ ṣugbọn iranlọwọ ni ibinu na yio jẹ fun ọ.

Aug. 23 - Sept. 22 (Virgo) Ọrọ kan yio ṣẹlẹ si ọ, ma ṣe mu ọrọ na ni pataki. Iwọ yio si ṣe orire nipa ọja rira lọsẹ yi.

Sept. 23 - Oct. 22 (Libra) O dara fun ọ lati ni ọrẹ ta bi alabaṣe lọsẹ yi, tabi Iyawo lọsẹ yi.

Oct. 23 - Nov. 21 (Scorpio) Ọsẹ yi dara fun ọ lati ni ajumọṣe

Nov. 22 - Dec. 22 (Sagittarius) Ẹnikan ti o ti ṣe keta rẹ ni Ilẹ okere, yio tun pada wa lati ma ja fun ọ.

Dec. 23 - Jan. 20 (Capricorn) Maṣe ni aniyan lati ra nkan titun ni a k o k o yi, nitori owo yio ja ọ ni irọ ninu ọsẹ yi.

Jan. 21 - Feb. 19 (Aquarius) Aya fi ki o ti pari awọn isẹ to wa nilẹ fun ọ lati ṣe ki ọ s a n to pọn, bi bẹkọ ko ni ṣeṣe mọ.

Feb. 20 - Mar. 20 (Pisces) Iwọ yio fi ti rẹ silẹ gbọ ti ẹlomiran ninu ọsẹ yi. Inu rẹ yio si ma dun si.

Mar. 21 - April 20 (Aries) Ọpọ ninu awọn nkan ti o ti ngba lero lati ṣe, ni ọwọ rẹ yio tẹ k u k u Ida rẹ ninu ọ sẹ yi.

April 21 - May 22 (Taurus) Gbogbo ọjọ oni yio dara fun ọ delẹ

May 23 - June 21 (Gemini) Iwọ yio gbọ irohin pe, alafia ni ọrẹ tabi ara rẹ kan wa.

June 22 - July 22 (Cancer) Gbogbo nkan ti o ba ṣe lọsẹ yi ni yio ma ni ilọsiwaju.

---


### GBANGBA DEKUN!! KEDERE! BEWO!!




## PORAL

OLUBORI EGBOGI "IKỌ"

Bi Amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jube lọ, awọn egbogi rọbi-rọbi ko le ṣe iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni "PORAL" ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ otutu' Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ Ile, Ikọ ti o ma mu enia tu kẹlẹbẹ nigbakugba lati inu 'Ifun' wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu--Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara re ni kiakia, igbaaiya tabi ọna-ọfun rẹ ti oma nho yio duro, "IKỌ" rẹ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pẹlu Alafia de.

Bere egbogi yi ni Ṣọbu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**


# Imoran lati le gbe pelu Alafia

Lati Enu:- JAMES ALAGBA

O HA TỌ KI NSALỌ KURO LỌDỌ BABA MI BI?

---

IBERE:- Omuti paraku ni baba mi, bi o ba si yo bi olokugbẹ, gbogbo iwa ti o nhu lo njẹ itiju fun mi. Lọpẹ yi ti o yo repẹtẹ, nṣe lo fi iwa rẹ ba mi jẹ larin awọn ojulumọ mi gbogbo. Ọna wo ni ki ngba lati fi tun ara mi ṣe lọdọ awọn ojulumọ mi, tabi ki nsa lọ fun?

Emi ni,
ILARO. ISIAKA JINADU.

IDAHUN: O ṣe mi lanu fun ọ jọjọ fun ọrọ ti o gbe silẹ yi, iwọ ti o wa ni ọmọ ọdun mejidilogun ti o ti bẹrẹ si tiju awọn iwa aidara ti awọn obi rẹ nhu, bi o ba sa lọ, iyẹn ko tun nkan ṣe, nitori ko ni jẹki o le kọ ẹkọ ni pa iru iwa ti baba rẹ na nhu. Mo mọ pe oju yio ma ti o niwaju awọn ọrẹ rẹ. Ṣugbọn awọn ọrẹ rẹ na ko nṣe ọmọluwabi lati ma fi oju ẹgan wo ọ nitori ohun ti baba rẹ ṣe. Ohun to dara ki o ṣe ni pe, ki ofi ẹjọ baba rẹ sun awọn agbalagba ki nwọn pe e, ki nwọn si ba ṣọrọ. Iwọ ko gbọdọ salọ kuro lọdọ baba rẹ nitoripe o ni lati ma mojuto. O tọ wipe ki iwọ papa ba baba rẹ sọrọ, ki o si sọ gẹgẹbi iwa rẹ ti ṣe nfi ọ ṣe ẹsin kakiri ilu, o si le tipasẹ bẹ kọ ọti silẹ, o dara ki o ṣe suru pẹlu baba rẹ, ki o si wa ọna ti yio fi kọ owo ọti mimu silẹ.

AKIYESI:—Mo fi eleyi tun ran gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ leti pe ohun kohun ti o ba ru nyin loju bi iru eleyi, ẹ kọwe si Emi James Alagba, ngo fun yin ni ọpọlọpọ amọran lori ohun ti ẹ ba bere, kọwe si James Alagba c/o Olotu Irohin Imọlẹ 16, Bamgboṣe St. Lagos.

---




# Owo eni lafi ntun iwa eni se

Bi ailowo lọwọ ba nda ọ lamu, bi siromobi ba mba ọ lọkan jẹ, tabi airişẹşe lo nyọ ọ lẹnu, tabi o tilẹ nşişẹ na owọ işẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo koko berẹ. Ki o si tun ọna rẹ şe, kọwe pẹlu şile m ẹ w a abọ 10/6d pẹlu Sitampu (Stamp) oni tọrọ 3d fun ohun to fa ati atunşe adariwo na ni ọdọ:—

AWORAWỌ
P. O. BOX 166, YABA - NIGERIA



# PAYAL

Ojulowo Egbogi k o k o r o ti o lagbara gidigidi fun "Ipara" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba, Alefọ. Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi adajinọ egbo, ekusẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara sisu, Akọ Inarun ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tatanbulu şe ti wọa npe ni "PAYAL" wo larin ijọ mẹta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu. E g b o g i ipara yi ki se awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si gişe iye meji ninu rẹ eleyi si yatọ patapata si awọn ogerẹmiti adimọw ọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereke gbogbo pẹlu. Orişi meji rẹ lowa. Kekere ati Nla.

Bere Egbogi Ajẹbina Payal yi ni Şọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ŞỌBU IBADAN:-
IŞE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADE ỌYO IBADAN



# KERE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Eku afojuba Egbogi pataki ti ase iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ Arun wọnyi-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o sọpọ ni ode isisinyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ, TULU, LUKULUKU, OTUTU, IGBAA'YA ARA R RO ati OTUTU ỌRERẸN pẹlu AKOKORO. Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi, Irohin ko to Afojuba yin.

Bere ise t ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin. Odau hanwun. Ẹ o ri işẹ rẹ lehin işẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745
LAGOS


## O BẸRẸ LATI OJU EWE KEJI

Ekini gbọ o gba oni suru owo ti o yarọ ni Ogun fi ta lọrọ, o kọlẹ, o kan asẹ, ogbe Ọmọge orekẹlẹwa Ọ l ọ m u gọgọgọ, gbogbo ile rẹ nho yun gba fun Ọ m o, E k e j i gbọ şugbọn ko gba, o fi iponju la ọbẹ gbigbona Esu fun ni ọwọ gbigbona, pẹlu gbogbo owo rẹ kọ ni alafia, ile ati ọna rẹ dahoro mọ loju ki o to fi ile aiye silẹ nitorina ẹnyin ọmọ mi ki nse alaye fun nyin ni kekere nitoripe Babalawo teini ki şe gb'aşọ, gb'obi gba apa dari ẹran ajogun ba ni. Owo ni ẹduo ọkan ẹyin, ọna kọna ni ẹ si ngba lati wa, ẹ o ri şugbọn pẹlu suru ni.

## ŞEBOTIMỌ NI ALAGBA, ỌNA WO NI A O FI RI OWO NA

Babalawo si da lo hun pe, tai ni ri owo kọ, şugbọn ọna yio jin ki ẹ to ri, ti o ba di oruganjọ ki ẹ gba ẹhin odi, ki ẹ si ma tẹle ọna g b o o r o kan ti o fi ori sọ odi Ilu, ẹ o ri ọkunrin arugbo kan ti ori rẹ dabi ikoko odu oro kẹrọ ti o ba bere lọwọ nyin, ẹ ma şe binu, ẹ da lo hun towọtowọ nitoripe on ni yio fi IGBO O W O ATI OLA" han nyin. Ş u g b ọ n ti ẹ ba nsọrọ lọwọ, obinrin arẹwa kan yio tun yọ si nyin, ohunkohun ti o ba sọ ẹ ma da lohun, ẹtan ni.

## NWỌN GBỌ, NWỌN SI MU ỌNA PỌN

Werewere ni awọn mejeji si lọ dagbere ni ile, nwọn si mu ọna ajo nwọn pọn, wọn ko iti rin ju ibusọ kan lọ ti wọn fi yi sẹhin odi Ilu, ni wọn ba ntẹle ọna gbooro na lọ.

A K I Y E S I:- Lọsẹ to mbọ lagbara Ọ l ọ r u n ẹ o ma ka apa kẹta (3)


# Ibanuje Tabi Ironu re de Opin Ayo de!

BERE EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:-

## "CORSIVERA"

Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti ase ni pataki fun:-

"ARỌN KINIŞA TABI ARỌN LATỌNLATỌN" MEJI RẸ KOSI.

Bere lọdọ awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**



# MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ti a se ni ase pe fun awọn Ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn işẹ ribi ribi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara fun igbona, ikọ, otutu A i p e r i, Osi inu Ọmọde, jẹdijẹdi, kokoro ori Ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ọmọde ko ma nsun fọnfọn o mu ki ẹhin bibu jẹ irọ run fun awọn ọmọde osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu won dan ni awọ. Ẹnyin Abiyamọ, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti ko şe mani fun awọn ọmọde I j o f a r a lewu pupọ, tete lọ ra tiro ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.




Igo kekee re jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROS.

| | |
|---|---|
| 6, Balogun Street, West 34, | Docemo Street |
| Lagos Nigeria | Lagos |
| Phone 22515 | Phone 24247 |


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 6, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985 Olotu E. A. Adeniji 31, Tejuoso Street Suru-Lere YABA.